1.0. ÀKÓJỌPỌ̀ ÀBÁJÁDE ILÉ IṢẸ́ AYẸ̀WÉ OWÓ-WÒ ÀBGÀ LÓRÍ ÈTÒ ÌṢÚNÁ ÌJỌBA ÌPÍNLẸ̀ ÈKÌTÌ FÚN ỌDÚN 2024

ÌṢÀMÚLÒ ÈTÒ ÌṢÚNÁ.

- Ètò ìṣúná ọdún 2024 jẹ́ ètò ìṣúná èyí tí owó tó wọlé àti owó ìná yóò jẹ́ iye owó tó lé ní Bílíọ̀nù Ọ̀rìnlé lọ́ọ̀dúnrún dín mẹ́jọ (₦372,154,157,569.39).
- Iye owó tó wọlé ní pàtó ní ọdún náà lé ní Bílíọ̀nù Ọ̀jìlénírínwó lé méjì Náírà (₦442,141,088,374.03) nígbà tí owó-ìná lé ní Bílíọ̀nù Ọ̀rìnlélọ́ọ̀dúnrún dín mẹ́jọ Náírà (₦372,137,551,542.97) tí ó túmọ̀ sí ìṣàmúlò ètò ìsúná ìdá okòó lé ní ọgọ́rin-in dín ẹyọ̀kan (119%) fún owó tó wọlé nígbàtí owó-ìná jẹ́ ìdá ọgọ́rùn-ún (100%)
- Iye owó àtigbàdégbà tó wọlé dín díè ní Bílíọ̀nù Ọ̀ọ́dúnrún lé méjì dín lọ́gbọ̀n àbọ̀ Náírà (₦328,313,216,719.13) nígbàtí owó tí a lérò pé yóò wọlé lé ní Bílíọ̀nù Ọ̀tàlénígba dín mẹ́rin Náírà (₦256,380,166,575.94) tí ó túmọ̀ sí ìṣàmúlò ètò ìṣúná ìdá Ọgọ́fà lé mẹ́jọ (128%) èyí tí ó gbé pẹ́ẹ̀lí ju ti ọdún tó kọjá tó jẹ́ ìdá mẹ́rinlélọ́gọ́fà.(124%)
- Ọ̀pọ̀ owó àtigbàdégbà tó wọlé ló wọlé láti àsùwọ̀n Ìjọba àpapọ̀ èyí tí iye rẹ̀ lé ní Bílíọ̀nù Ọ̀rìnlénígba lé méje Náírà (₦287,226,899,255.54) tó túmọ̀sí ìdá mẹ́tà dín láàádọ́rùn-ún àti ìpín mọ́kàndín láàádọ́ta(87.49%) iye owó àtigbàdégbà tó wọlé lọ́dún náà.
- Ìpín owó tó wọlé sí àpò Ìjọba Ìpínlè lọ́dún tí ó kọjá tí iye rẹ̀ lé ní Bílíọ̀nù mẹ́tà lé lọ́gọ́ta àbọ̀ Náírà (₦63,682,711,760.64) kéré níye sí tọ́dún tí a ń gbé yẹ̀wò tó jẹ́ iye tó lé díẹ̀ ní Bílíọ̀nù lgba lé márùn-ún dín lọ́gbọ̀n Náírà (₦225,342,398.51) tí iye tó fi gbé pẹ́ẹ̀lí sókè sí i jẹ́ ìdá ọgọ́fà lé méjọ nínú ìdá ọgọ́rùn-rún (128%). Àpapọ̀ owó tó wọlé láti àsùwọ̀n Ìjọba Àpapọ̀ sí àpò Ìjọba Ìpínlẹ̀ ní ọdún náà tó lé ní Bílíọ̀nù Igba lé márùn-ún dín lọ́gbọ̀n (₦225,342,398,398.51) èyí tí ó lọ sókè is i ju ti ọdún tó kọjá ní iye tó lé ní Bílíọ̀nù Mẹ́tà lé lọ́gọ́ta àbọ̀ Náírà (₦63,682,711,760.64) tí iye tó fi gbé sókè sii lé ní Bílíọ̀nù Mọ́kànlé lọ́gọ́jọ àbọ̀ Náírà (₦161,659,68S6,637.87)
- Iye owó tó wọlé lábẹ́lé ní ọdún 2023 tó lé ní Bílíọ̀nù Mọ̀kànlélọ́gbọ́n àbọ̀ (₦31,792,404,887.47) kéré níye sí owó tó wọlé ní ọdún tí à ń gbé yẹ̀wò yíí tó lé ní Bílíọ̀nù Mérìn lé lọ́gbọ̀n àbọ̀ Náírà (₦34,671,046,808.76) tó túmọ̀ sí ìdá mẹ́sàn-án lé díẹ̀ (9.05%) tó fi gbé sókè sii.

  Àwọn onírurú owó míràn tó wọlé gbé sókè daadaa láti Mílíọ̀nù Irínwó lé mẹ́rinlélọ́gọ́rin àbọ̀ Náírà (₦484,502,076.47) sí Bílíọ̀nù mẹ́fà lé díè Náírà (₦6,352,520,954.83S) èyí tí ìdá tó fí gbé sókè sii jẹ́ ìdá ọgọ́fà lé mọ́kànlá (1211.14%)

- Owóyàá láti òkèèrè lọ sókè sii láti Bílíọ̀nù Mẹ́sàn-án lé díẹ̀ (₦907,791,172;66) ní ọdún 2023 sí Bílíọ̀nù mẹ́rìndínlógún lé díẹ̀ (₦16,198,951,097) ní ọdún 2024. Owóyàá lábẹ́lé náà gbé sókè láti Bílíọ̀nù kan àbọ̀ lé díẹ̀ (₦1,558,096,256.97) ní ọdún 2023 sí iye owó tó lé ní Bílíọ̀nù Méjì àbọ̀ ní ọdún 2024(₦2,722,353,990.97)
- Owó fún àkànṣe-iṣẹ́ fún ọdún náà tí àpapọ̀ rẹ̀ lé ní Bílíọ̀nù mẹ́rìnlàádórin (₦74,133,707, 061.90) tí ó sì wà ní ìbámu pẹ̀lú iye owó tí a fojúsùn tó lé ní Bílíọ̀nù Mẹ́rìndínlọ́gọ́rin (₦76,059,826,399.64). Àbájáde èyí jẹ́ ìṣàmúlò ètò ìṣúná ìdá mẹ́ta dín lọ́gọ́rùn-ún (97%) èyí tó dín ní ìdá márùn-ún (5%) sí ti ọdún tó kọjá tó jẹ́ ìdá méjì lé lọ́gọ́rùn-ún (102%).
- Iye owó àtigbàdégbà fún ọdún 2024 jẹ́ Bílíọ̀nù Mẹ́tàlá lé nígba lé díẹ̀ (₦213,203,344,540.88) tó túmọ̀ sí ìdá méjì dín lọ́gọ́fà (118%) ìṣàmúlò ètò ìṣúná. A ṣe àkíyésí pé iye owó-ìná jẹ́ ìdá méjì dín láàdọ́ta lé díẹ̀ (48.22%) iye owó tó wọlé ní pàtó àti ìdá tó dín díẹ̀ ní ìdá Márùn-ún dín lọ́gọ́rin iye owó àtigbàdégbà (64.94%) fún ọdún tí à ń gbé yẹ̀wò.

- Owo-ìná ní pàtó fún ọdún tí à ń gbé yẹ̀wò dín díẹ̀ ní Ọgọ́ta Bílíọ̀nù dín ẹyọkan Náírà (₦158,934,207.09) tó jẹ́ ìdá mẹ́tàlé lọ́gọ́rin (83%) ìṣàmúlò ètò ìṣúná, ìdá mẹ́rìndínlógójì (36%) àpapọ̀ owó tó wọlé, ìdá Igba lé mẹ́rìnlá (214%). Iye owó tó wọlé ní pàtó àti ìdá mẹ́tàlélógójì (43%) àpapọ̀ owó-ìná fún ọdún náà.
  Ni ọdùn tí à ń gbé yẹ̀wò, iye owó tí a lérò láti ná bi owó-ìná àtìgbàdégbà jẹ́ ìpín 1:1.06, nígbà tí ìpín ní pàtó ní ọdún náà jẹ́ ìpín 0.75:1. Àbádáje èyí ni pé ètò ìṣúná ti ọdún tí à ń gbé yèwò dára ju ti ọdún tó kọ já lọ.
- Ilé-iṣẹ́ Ayẹ̀wé-owó-wò ṣe àkíyèsí pé ètò ìṣúná ti ọdún 2024 kò kúnjú ìwọ̀n tó nítorí pé iye owó tí wọ́n lérò pé yóò wọlé tó lé ní Bílíọ̀nù Mẹ́rìn dín lọ́gọ́rin (₦76,059,026,399.64) àti iye owó tí wón gbèrò láti ná tó lé ní Bílíọ̀nù mọ́kànlé láàdọ́wá (₦191,799,820,229.90) tó já sí gbèsè iye owó tó lé ní Bílíọ̀nù márùn-ún dín lọ́gọ́fà àbọ̀ (₦115,739,993,830.26). Gbèsè yìí tó jẹ́ ìdá tó lé ní ọgọ́ta nínú ìdá ọgọ́rùn-ún (60.34%) iye owó-ìná ni wọn kò rò tẹ́lẹ̀ nígbà tí owó àjẹṣẹ́kù tó lé ní Bílíọ̀nù mọ́kàndínlógójì àbọ̀ Náírà ní ọdún 2023 kò tó san gbèsè náà

## 2.0. ÀKÍYÈSÍ ÀTI ÀBÁ ILÉ-IṢẸ́ AYÈWÉ-OWÓ-WÒ ÀGBÀ LÓRÍ ÌṢÀMÚLÒ ÈTÒ ÌṢÚNÁ

- Ìṣòro tó máa ń jẹyọ nípa ṣíṣe ètò ìṣúná lórí iye owó tí kò lè wọlé tí a tọ́ka sí ní àwọn ọdún tó kọjá lọ ni wọ́n ti ṣe àmọ́jútó rè. Síbẹ̀síbẹ̀, Ilé-iṣẹ́ wa ṣe àfihàn bí owó ṣe ń wọlé sí àpo Ìjọba Ìpínlẹ̀ ní ẹlẹ́kajẹ̀ka ṣì wà bákan náà. Fún àpẹrẹ, owó fún ìdókòwò nínú ètò ìṣúná tó jẹ́ ẹgbẹ̀rún mẹ́rìn lélógún Náírà (₦24,000).
- Iye owó-ìná tí wọ́n gbèrò láti ná tó jẹ́ ìdá méjìdínlógún nínu ìdá ọgọ́rùn-ún ni wọ́n ná tí èyí sì gbé sókè ju ìdá méwàá (10%) ní ọdún 2023. Síbẹ̀, ó ṣì bá àlàkalẹ̀ ìdá márùndínlógún tí SFTAS ṣe mu. Ó ṣe pàtàkì láti wá àwọn ọ̀nà míràn tí owó yóò ti máa wọlé kí owó tó ń wọlé sápò Ìjọba Ìpínlẹ̀ Èkìtì lè búrẹ́kẹ ṣi i
- Kí Ìjọba Ìpínlẹ̀ Èkìtì ṣe àfihàn àti ìpolongo àwọn ohun àmúsọrọ̀-ajé Ìpínlẹ̀ yíí fún àgbáyé rí nípa ṣíṣètò ìpàdé àpérò àti ìlanilóye lórí ètò ọrọ̀-ajé láti fa àwọn olùdásésílè lábẹ́lé àti lókè òkun wá sí Ìpínlẹ̀ yíí.

## 3.0. OWÓ TÓ WỌLÉ LÁBẸ́LÉ

- Iye owó tó wọlé lábẹ́lé ní ọdún 2024 tó jẹ́ owó tó lé ní Bílíọ̀nù Mẹ́rìnlélọ́gbọ̀n àbọ̀ Náírà (₦34,671,046,808.76) gbé pẹ́ẹ̀lí ju ti ọdún tó kọjá ní iye owó tó dín ní Bílíọ̀nù méta Náírà (₦2,878,641,921.29) èyí tó jẹ́ ìdá mẹ́sàn-án lé díẹ̀ (9.5%) nínú ìdá ọgọ́rùn-ún tí a bá fi wé ti ọdún 2023 tó lé ní Bílíọ̀nù Mọ́kànlélọ́gbọ̀n àbọ̀ (₦31,792,404,887.47).
- Owo tó wọlé lábẹ́lé ní ọdún tí à ń gbé yèwò yíí tó dín ní ìdá mẹ́sàn-án lé díẹ̀ (9.05%) dín kù níye tó pọ̀ tí à bá fi wé ti ọdún tó kọjá tó jẹ́ ìdá mọ́kàn dín láàádọ́rùn-ún (89%).
- Owó-orí tó wọlé lábẹ́lé tí kì í ṣe owó-orí láti ọ̀dọ̀ àwọn Ilé-Iṣẹ́ Ìjọba (MDAs, Parastatals and Tetiary Institutions) àti ilé-ẹ̀kọ́ gíga ní ọdún náà tó jẹ́ Bílíọ̀nù méjìdínlógún àbọ̀ Náírà (₦18,505,118,707.82) pẹ̀lú ìṣàmúlò ètò ìṣúná tó jẹ́ ìdá méjìléláàádọ́fà (112%). Èyí lọ sókè sii ní iye owó tó lé díẹ̀ ní Bílíọ̀nù méjì Náírà (₦2,00,112,699.99) tó jẹ́ ìdá méjìlá lé díẹ̀ (12.13%) tí a bá fi wé ti ọdún 2023 tó jẹ́ Bílíọ̀nù Mẹ́rìndínlógún àbọ̀ Náírà (16,503,006.007.83).
- Ó yẹ kí wọ́n gbé Ìgbìmọ̀ Apowó-wọlé kalẹ̀ láti ṣe ìjíròrò pẹ̀lú Ilé-Iṣẹ́ Ìjọba (MDAS) láti ṣe àlàkalẹ̀ ọ̀nà bí owó yóò ṣe máa wọlé. Ìwé àkọ́ọ́lẹ̀ olóṣooṣù nípa bí wọ́n ṣe pawó wọlé láti Ilé-Iṣẹ́ Ìjọba ni

wọ́n gbọ́dọ̀ máa mú ṣọ́wọ́ si Ìgbìmọ̀ Apowó-wọlé náà kí wọ́n sì ṣàlàyé ìdí tí owó kò fi wọlé lóṣù tí owó kó bá wọlé. Ìgbìmọ̀ náà sì gbọ́dọ̀ tètè wá ojútùú sí àwọn ìṣòro tí Ilé-Iṣẹ́ Ìjọba (MDAS) bá ń dojúkọ.

- Àpapọ̀ owó-orí tó wọlé ní ọdún náà lé díẹ̀ ní Bílíọ̀nù mẹ́rìndínlógún (₦16,166,928,100.94) nínú èyí tí Bílíọ̀nù Mẹ́sàn-án àbọ̀ lé díẹ̀ (₦9,613,946,816.59) tó jẹ́ ìdá márùn-ún dín lógójì lé díẹ̀ (35.32%) jẹ́ owó-orí tó wọlé láti ọ̀dọ̀ àwọn òṣìṣẹ́ Ìjọba nígbà tí iye owó tó lé ní Irínwó lé mẹ́ta àbọ̀ Mílíọ̀nù (₦403,728,016.92) wọlé láti ọ̀dọ̀ àwọn Ayẹ̀wé-owó-wò, tí Bílíọ̀nù méjì lé díẹ̀ (₦2,081,971,311.19)wọlé láti oríṣiríṣi àwọn iṣẹ́ tí kò súyọ nínú ètò ìṣúná.
- Owó-orí tó wọlé láti ọ̀dọ̀ àwọn tí kì í ṣe òṣìṣẹ́ Ìjọba gbé sókè sii láti iye owó tó lé ní Ọ̀rìnlélẹ́ẹ̀dẹ́gbẹ̀ta lé mẹ́ta Mílíọ̀nù Náírà (₦586,319,318.21) ní ọdún 2023 sí iye owó tó lé ní Mílíọ̀nù Ọ̀rìnlélẹ́ẹ̀dẹ́gbẹ̀rún lé méji Náírà (₦982,321,645.16) ní ọdún 2024. Èyí jẹ́ ìdá méjì àti ìpín mẹ́ta lé lọ́gọ́rin (2.83%) nínu àròpò owó tó wọlé lábẹ́lé tí ó sì gbé pẹ́ẹ́lí jú tí ọdún tó kọjá ní ìdá kan àti ìpín mẹ́jọ nínú ìdá ọgọ́rùn-ún (1.8%). Owó ìdàgbàsókè tó wọlé lọ́dún náà jẹ́ ìdá mẹ́ta àti ìpín mẹ́tàlá (3.13%) nínú ìdá ọgọ́rùn-ún owó tó wọlé lábẹ́lé gbé pẹ́ẹ́lí si i tí a bá fi wé ti ọdún tó kọjá lọ tó jẹ́ ìdá kan lé díẹ̀ (1.03%) ní ọdún 2021 ìdá méjì àti ìpín mẹ́tàdínlọ́gbọ̀n(2.27%) ní ọdún 2022 àti ìpín mọ́kànlélọ́gọ́ta (0.61%) ní ọdún 2023. Èyí fihàn pé Ilé-Iṣẹ́ tó ń powó wọlé lábẹ́lé nílò láti jára mọ́ṣẹ́ si i kí owó-orí tó ń wọlé láti ọ̀dọ̀ àwọn tí kì í ṣe òṣìṣẹ́ Ìjọba lè túnbọ̀ gbé pẹ́ẹ́lí si i.
  Ilé iṣẹ́ tó ń powó wọlé lábẹ́lé gbọ́dọ̀ ṣètò àlàkalẹ̀ àti àkọọ́lẹ̀ àwọn tó ń sanwó orí, bí wón ṣe ń san wọ́n wọlé, owó-orí tí wọ́n san àti èyí tí wọn kò san kí owó-orí lè búrẹ́kẹ si i. Ọ̀nà kan gbòógì tí owó-orí fi lè máa wọlé lọ́pọ̀ yanturu ni níní àkọọ́lẹ̀ tó péye.
- Mímú àwọn tí kì í ṣe òṣìṣẹ́ Ìjọba sanwó-orí déédéé ní ìrètí àti mú kí owó-orí tó ń wọlé búrẹ́kẹ si i, nípa báyìí, a gba Àjọ tó ń powó-orí wọlé ní ìmọ̀ràn láti ṣiṣẹ́ takuntakun láti mú kí àwọn tí kì í ṣe òṣìṣẹ́ Ìjọba máa sanwó-orí wọn déédéé àti bí ó ti yẹ.

## 4.0. PÍNPÍN OWÓ SÍ ÀWỌN ILÉ-IṢẸ́ ÌJỌBA ÀTI ẸKA ILÉ-IṢẸ́

- A ṣe àkíyèsí pé owó àfiṣiṣẹ́ àkànṣe àti owó-ìná ni a kò pín fún àwọn Ilé-Iṣẹ́ bí wọ́n ti ṣe àlàkalẹ̀ rẹ̀. Àwọn Ilé-Iṣẹ́ Ìjọba tí a ṣe àlàkalẹ̀ owó-ìná tí iye rẹ̀ jẹ́ Okòó dín márùn-ún lé lọ̀ọ̀ọ́dúnrún Mílíọ̀nù Náírà (₦315,000,000) ni wọn kò rí owó kànkan gbà ní gbogbo ọdún náà. Àwọn Ilé-Iṣẹ́ Ìjọba mìíràn tí wọ́n ṣe àlàkalẹ̀ iye owó tó lé ní Bílíọ̀nù mẹ́ta Náírà (₦3,171,224,735.22) ni wọn kò rí ju iye owó tó lé díẹ̀ ní Àádọ́jọ dín márùn-ún Mílíọ̀nù Náírà gbà (145,210,208.60) èyí tó jẹ́ ìdá tó lé díẹ̀ ní Ìdá Mẹ́tàlélógójì (43.27%) nínú ìdá ọgọ́rùn-ún.

## 5.0. ÀLÀKALẸ̀ OHUN ÌNI ÀTI GBÈSÈ

- Kò sí àjẹṣẹ́kù owó àkópamọ́ tí a ṣe àkíyèsí lópin ètò ìṣúná ọdún náà nígbà tí àjẹṣẹ́kù owó tó wà nínú àsùwọ̀n ìfowópamọ́ Ìjọba lé díẹ̀ ní Àádọ́rin Bílíọ̀nù Náírà (₦70,003,536,831.06) tí èyí sì gbé pẹ́ẹ́lí si i ju ti ọdún tó kọjá ní ìdá mẹ́ta lé lógójì lé díẹ̀ nínú ìdá Ọgọ́rùn-ún (43.27%) èyí tó jẹ́ owó tó lé díẹ̀ ní Ọgbọ̀n Bílíọ̀nù Náírà (₦30,289,372,237.25).
- Ó ṣe pàtàkì kí ètò tó múná dóko wà nípa ètò ìnáwó kí owó tó pọ̀ yanturu ma kàn máa wà lọ́wọ́ tàbí ní Báǹkì. Eléyìí máa jẹ́ kí á pàdánù owó tó yẹ kó wọlé láìfi owó bẹ́ẹ̀ dókòwò. Bí ìgbà bá ṣe rí àti bí Náírà ṣe ń lọ sókèsódò lágbàáyé yẹ fún àkíyèsí gẹ́gẹ́ bí a ti dábàá rẹ̀ nínú àkọọ́lẹ̀ wa ti tẹ́lẹ̀.
- Owóyàá Ìjọba Ìpínlẹ̀ látòkèèrè títí di ọjọ́ kọ́kànlélọ́gbọ̀n oṣù kejìlá ọdún 2024 (31st Dec 2024) jẹ́ owó tó lé ní Bílíọ̀nù Igba lé mẹ́fà Náírà (₦206,633,067,613.68) nígbà tí owóyàá lábẹ́lé lé díẹ̀ ní Bílíọ̀nù mọkàndínlógójì Náírà (₦39,076,772,300.55). Àròpò gbogbo owóyàá ọdún náà jẹ́ iye owó

tó lé ní Bílíọ̀nù àádọ́ta dín márùn-ún lé nígba Náírà (₦245,709,789,914.23) tó dín ní ìdá márùn-ún lé láàdọ́ta (55.22%) sí ti ọdún tó kọja tó lé ní ìdá méjìdínlọ́gọ́fà (118.79%).

- Àwọn gbèsè mìíràn tí Ìjọba Ìpínlẹ̀ jẹ títí di ọjọ́ kọ̀kànlélọ́gbọ̀n oṣù kejìlá ọdún 2024 (31st Dec 2024) lé ní Bílíọ̀nù Méjìdínlọ́gbọ̀n Náírà (₦28,048,604,327.16). tí a bá ṣe àròpọ̀ gbogbo gbèsè náà papọ̀ yóò jẹ́ iye owó tó lé ni Bílíọ̀nù Ọ̀tàlénígba Náírà (₦260, 161,784,954.73).
- Àròpọ̀ owóyàá (lókèèrè àti lábẹ́lé )tó wọlé fún Ìjọba Ìpínlẹ̀ lọ́dún náà lé ní Bílíọ̀nù Méjì àbọ̀ Náírà(#2,722,353,900.97)nígbà tí owóyàá tí Ìjọba san padà lé ní Bílíọ̀nù Àádọ́rin dínkan àbọ̀ Náírà(#69,573,558,140.24) èyí tí Bílíọ̀nù Ọ̀kànlélọ́góta Náírà dín díẹ̀(#60,902,295,417.44) jẹ́ àsanpadà owóyàá lábẹ́lé nígbà tí Mílíọ̀nù Mẹ́jọ àbọ̀ Náírà lé díẹ̀(#8,671,262,722.80) jẹ́ àsanpadà owóyàá látòkèèrè lọ́dún náà.

- Àkíyèsí Ilé-Iṣẹ́ Ayẹ̀wé-owó-wò ni pé ní ọdún náà gbèsè sí owó tó wọlé sí àpò Ìjọba Ìpínlẹ̀ títí di ọjọ́ kọ̀kàndínlọ́gbọ̀n oṣù kejìlá ọdún náà (31st Dec. 2024) jẹ́ ìdá mẹ́tàlélọ́gọta lé díẹ̀ (63.51%). Àdínkù gbese bá ti ọdún náà tí a bá fi wé ti ọdún tó kọjá lọ tó jẹ́ ìdá tó lé ní ìdá ọgọ́fà dín méjì (118.75%).
- Àkíyèsí Ilé-Iṣẹ́ Ayẹ̀wé-owó-wò ni pé Ìjọba gbìyànjú nípa sísan gbèsè padà ní ọdún 2024 nítorí pé àsanpadà gbèsè gbé sókè ju ti ọdún tó kọja lọ.
- Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àsanpadà gbèsè gbé pẹ́ẹ́lí ju ti tẹ́lẹ̀ lọ síbẹ̀ kò yẹ kí Ìjọba Ìpínlẹ̀ máa tẹ̀síwájú láti máa gbẹ́kẹ̀lé gbèsè jíjẹ fún ṣíṣe ètò ìnáwó fún ohun èlò rẹ̀ bí  bẹ́ẹ̀ kọ́, láìpẹ́ láìjìnà gbèsè Ìjọba yóò kọjá àfaradà.

## 6.0. ṢÍṢE ÀMÚLÒ ÈTÒ ÌNÁWÓ TI IPSAS

- Ìgbésẹ̀ tó làmìlaka ni Ìjọba ti gbé nípa ṣíṣe àmúlò ètò ìnáwó (IPSAS). Ṣíṣe àmúlò àlàkalẹ̀ (IPSAS) fún ọdún 2023 ṣì ń tẹ̀síwájú títí di báyìí.
- Ṣíṣe ìgbélé òṣùwọ̀n fún ọ̀hún ìní èyí tó ṣe kókó nípa gbígbé ètò náà kalẹ̀ ni wọ́n ti ṣe àmúlò rẹ̀.
- Àwọn akọ́ṣẹ́mọ́ṣẹ́ bí àwọn wọnlẹ̀-wọnlẹ̀, adíye- lé dúkìá àti àwọn mìíràn ni wọ́n gbọ́dọ̀ kópa nínú ìdíye- lé ohun ìní láti mú àdínkù bá owó tí yóò máa ná Ìjọba  gẹ́gẹ́ bí a ti dábàá rẹ̀ nínú àkọ́ọ́lẹ̀ wa ti tẹ́lẹ̀.

## PÍNPÍN ÌDÁ MẸ́WÀÁ OWÓ TÓ WỌLÉ LÁBẸ́LÉ SÍ ÀWỌN ÌJỌBA ÌBÍLẸ̀

- Àwọn Ìjọba Ìbilẹ̀ ní ẹ̀tọ́ sí ìdá mẹ́wàá owó tó bá wọlé lábẹ́lé sí àpò Ìjọba Ìpínlẹ̀. Ní ọdún tí a ń gbé yẹ̀wò yìí Ilé-Iṣẹ́ tó n ṣètò ìnáwó Ìjọba (Accountant General) ṣàfihàn owó tí wọ́n san sí àpò àwọn Ìjọba Ìbílẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ìdá mẹ́wàá tí iye rẹ̀ jẹ́ Bílíọ̀nù kan àbọ̀ Náírà lé díẹ̀ (₦1,613,478,820.82). Ó ṣe pàtàkì kí wọ́n fún àwọn Ìjọba Ìbílẹ̀ lówó tó tọ́ sí wọn déédéé kí ìgbáyé-gbádùn lè wà fún àwọn ènìyàn lẹ́sẹ̀ kùkú.

## 7.0. FÍFỌWỌ́SÍ SÍSAN OWÓ ÌFẸ̀YÌNTÌ

- Ní ọdún tí a ń gbé yẹ̀wò yìí, ìwé fún sísan owó ìfẹ̀yìntì oṣooṣù tí iye owó ibẹ̀ lé ní Bílíọ̀nù kan (₦1,106,255,195.75) àti owó ìfẹ̀yìntì(gratuity) tí iye rẹ̀ dín díẹ̀ ni Bílíọ̀nù mẹ́rin Náírà (₦3,871,980,789.48) ni a fọwọ́sí fún sísan fún àwọn òṣìṣẹ́- fẹ̀yìntì

8.0. OWÓ TÓ SỌNÙ

Owó tí iye rẹ̀ lé ní Mílíọ̀nù Ọgọ́rùn-ún lé méje Náírà (₦107,384,799.20) tí ó jẹ́ owó tó sọnù ní àwọn Ilé-Iṣẹ́ Ìjọba (MDA'S) tí ọ̀rọ̀ náà kàn ni wọn kò ì tîì ṣàwárí owó náà pẹ̀lú gbogbo àkọọ́lẹ̀ Ilé-Iṣẹ́ yìí nípa rẹ̀ látẹ̀yìn wá.

10.0 ÀWỌN ÌDÓKÒWÒ ÌJỌBA

- Ní ọdún tí a ń ṣe àgbéyẹ̀wò rẹ̀ yìí, àwọn Ìdókòwò Ìjọba méta tí a ṣe àfihàn rẹ̀ ni àpapọ̀ iye owó rẹ̀ dín ní Bílíọ̀nù Mẹ́rin Náírà (₦3,899,737,092.10), èyí gbé pẹ́ẹ̀lí sókè sí i ju ti ọdún 2023 tí iye owó rẹ̀ lé díẹ̀ ní Bílíọ̀nù Méjì Náírà (₦2,276,424,624.00). Èyí wáyé nítorí Ìpín Ìdókòwò àwọn Ilé Iṣẹ́ tí wọ́n lọ́wọ́ nínú ìtàjà àti Ìpín Ìdókòwò ní Ilé Ìfowópamọ́ (Access, First bank) ati LAFARGE).

11.0. ÀTÚNYẸ̀WỌ̀ ÌṢAKÓSO ÌṢÈTÒ ÌNÁWỌ̀

- Ó yẹ kí wọn ṣe àtúnyẹwò iṣákóso étò ináwó Ìjọba tí wọn ń lò báyìi ni ibámu pẹ̀lú étò ìṣákóso ètò ìnáwó tí wọn ṣẹ̀ṣẹ̀ ṣe kí wọ́n sì ṣe àgbékalẹ kòkáárí Ilé-iṣé Ayẹ̀wố-owó-wò ti abẹ́lé (Central Internal Audit)
- Àwọn ìwé iṣákóso Ètò Ìnáwó kò sí lórí àtẹ fún rirà yálà ní Ilé- Iṣẹ́ Ìjọba tàbí Ilé- Èkọ́ṣẹ́ fún àwọn Òṣìṣẹ́ (Civil Service Commission or Office of Establishment and training).

- Ki iwe iṣákóso Ètò ináwó wà lórí Ìkànnì Ìjọba Ìpínlẹ̀ Èkìtì fún àǹfààní àwọn tó bá nílò rẹ̀.

12.0. ÈTÒ ÌṢÀKÓSO LÁBẸ́LÉ

- Ètò iṣákóso lábẹ́lé ń ṣe déédé pàápàá fún Ilé-Iṣé Ayẹ̀wé-owó-wò lábẹ́lé
- Àkọólẹ̀ àyẹ̀wò olóṣooṣù Ayẹ̀wó-owó-wò lábẹ́lé láti àwọn Ilé-iṣé Ìjọba kò wà ní ìbámu pẹ̀lu ohun tí a jírórò lé lóri tẹ́le
- Àkọ́ọ́lẹ̀ tó kúnjú ìwọ̀n tó si báramu ni ó gbọ́đọ̀ jẹ́ àkọ́ọ́lè áyẹ̀wò olóṣooṣù àwọn Ayẹ̀wó-owó-wó lábẹ́lé

13.0. ÀWỌN OHUN TÓ Ń FẸ́ AMÓJÚTÓ NÍ ILÉ-IṢẸ́ AYẸ̀WÉ-OWÓ-WÒ ÀGBÀ TI ÌPÍNLẸ ÈKÌTÌ

- Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ áti idàgbàsokė àwọn òṣìṣẹ́
- Ọkọ̀ àfiṣiṣé kò tó
- Ọ́fíìsì fún àwọn òṣìṣẹ́
- Àga, Tábìlì àti àwọn ohun èlò fún iṣẹ́ ní Ilé-Iṣẹ́ yìí.

Adéùyá, Victor Olúwọlé (ACArb,FCCFI, FCA)
FRC/2021/009/00000023353
Auditor-General,
Èkìtì State.